# Èrò-Ìjìnlẹ̀ Yorùbá Nípa Olódùmarè Ibrahim Bidemi

**TABI-AGORO** Ayobami Mistura, Ph.D.
ayobamimistura2020@gmail.com
08033894332
Department of Yorùbá Studies,
Tai Solarin University of Education, Ijagun, Ogun State
Nigeria

**ISHOLA** Sauban Alade, Ph.D
isholasa@fceiwo.edu.ng/isholasauban@gmail.com
Department of Yorùbá Studies, Federal College of Education, Ìwó.
08063740135

**Àṣamọ̀**

Àfojúsùn ìwádìí yìí ni láti ṣàgbéyẹ̀wò èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè. Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ó ṣe pàtàkì láti ṣe àfihàn bí èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ Yorùbá ṣe gbé ara lé Oríkì Olódùmarè, gẹ́gẹ́ bí èyí tí ń ṣe atọ́nà wọn lórí ìgbé ayé wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ti ṣiṣẹ́ lórí ìgbàgbọ́ Yorùbá, díẹ̀ nínú wọn ni ó dojú kọ ìwádìí nípa Oríkì Olódùmarè láti ṣe àfihàn ojú-àmúwayé àwọn Yorùbá nípa àbùdá Olódùmarè. Ìwádìí yìí ṣe ìtúpalẹ̀ tí ó jinlẹ̀ lórí ewì ìgbàlódé Ọlánrewájú Adépọ̀jù tí ó jẹ mọ́ Oríkì Olódùmarè níbi tí iṣẹ́ rẹ̀ ti ṣe àfihàn èrò àwọn Yorùbá nípa Ọlọ́run. Nínú ìtúpalẹ̀ tí a ṣe fún iṣẹ́ akéwì yìí, ó hàn gbangba pé àwọn orúkọ tí Yorùbá ń pè Olódùmarè àti Oríkì tí wọ́n máa ń fi kì í jẹ́ ọ̀nà tí wọ́n ń gbà ṣe àgbékalẹ̀ èrò wọn nípa àbùdá Ọlọ́run. Àbájáde pàtàkì tí ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé, oríṣìíríṣìí èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè ni wọ́n máa ń ṣe àfihàn rẹ̀ nínú Oríkì tí wọ́n ń fi kì Í. Ojú tí àwọn Yorùbá fi ń wo Olódùmarè ni wọ́n fi gbà Á bí Alágbàwí, Adẹ́dàá, Aṣẹ̀dá, àti Ọba-Àìkú gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú Oríkì Olódùmarè tí a rí nínú àwo ewì Ọlánrewájú Adépọ̀jù.

**Kókó-Ọ̀rọ̀:** Olódùmarè, àwọn òrìṣà, ẹ̀mí-àìrí, Alágbára, Ọba-Àìkú-Àìṣá

**Abstract**

The focus of this research is to examine the thought and belief of Yorùbá about Olódùmarè. This paper examines the thought and belief of Yorùbá about Olódùmarè. Previous scholars have worked tremendously on Yorùbás' belief, but very few focused on Oríkì Olódùmarè to depict Yorùbá world-view on the characteristics of Olódùmarè. This study adopted critical analysis to fill the gaps created by the previous researchers. This paper surveyed Ọlánrewájú Adépọ̀jù's poems as one of the popular poets in Yorùbá whose works reveal the conception of Yorùbá about God. In this study, exposition of Yorùbá thughts and conception about Olódùmarè would project how the thughts of Yorùbá about God is established through chanting of Oríkì Olódùmarè and several names given to Him in Yorùbá cosmology. The major findings of this study are that there seems to be five dominant thematic preoccupations in Olanrewaju Adepoju's Oríkì in respect to Olódùmarè. Portrayal of Olodumare in Olanrewaju Adepoju's poetry further describes him as a competent holder and repertoire of Yorùbá philosophical thoughts and belief. More importantly, his inclination is in tandem with what the proponents of authorial intention for analysis of literary works. Their framework entails God's portrayal as Creator,

Originator, Omnipotent, Benevolent and Immortal as intended in the chanting of Olódùmarè's Oríkì by Olanrewaju Adepoju. The five themes as seen in Oríkì Olódùmarè of Olanrewaju Adepoju's poetry shows that Yorùbá people see God as Supernatural, Superimposed grandeur being and Supreme whose impact though not seen is felt in every nook and cranny of both physical and spiritual lives of people and other creatures.

Keywords: Olódùmarè, Divinities, Supernatural, Grandeur, and Omnipotent-Omniscience

## Ìfáárà

Ìwádìí yìí jẹ́ mọ́ àyẹ̀wò èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè. Onírúurú nǹkan ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ nínú rẹ̀, ṣùgbọ́n èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ wọn nípa Olódùmarè ta yọ ojú-àmúwayé wọn nípa àwọn nǹkan mìíràn. Olúborí èrò-ìjìnlẹ̀ wọn Olódùmarè ló dá gbogbo nǹkan tí a lè rí àti èyí tí a kò rí. Èrò-ìjìnlẹ̀ wọn yìí ló fà á tí ó fi nira fún láméètọ́ láti pààlà láàrin ẹ̀sìn ìbílẹ̀ àti àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyàtọ̀ tó lọ̀ọ̀rìn wà láàrin àṣà àti ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìdí tí ó fir í bẹ́ẹ̀ ni pé, gbogbo ìgbòkègbodò àti ètò ìgbé ayé àwọn Yorùbá gbára lé èrò-ìjìnlẹ̀ wọn nípa Ọlọ́run. Èrò-ìjìnlẹ̀ wọn nípa Ọlọ́run náà ni ó sì bí onírúurú ẹ̀sìn ìbílẹ̀ tí wọ́n ń sìn. Nítorí náà, kò sí abala ètò ìgbé ayé àwọn Yorùbá tí a lè yẹ̀ wò, tí a kò ní rí àpẹẹrẹ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn níbẹ̀.Nínú iṣẹ́ yìí, lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni a ní lọ́kàn láti fi ṣe òdìwọ̀n ìwádìí nípa èrò-ìjìnlẹ̀ àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè. Ewì alohùn tí ó sì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn lítíréṣọ̀ alohùn náà ni a yàn láàyò. A lo oríkì láti ṣe àfihàn ìlànà tí àwọn Yorùbá ń gbà gbé èrò-ìjìnlẹ̀ wọn kalẹ̀ nípa Olódùmarè. A ṣe àṣàyàn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn apohùn nínú àwùjọ Yorùbá láti ṣe àyẹ̀wò àgbékalẹ̀ oríkì Olódùmarè tó hànde nínú àwọn ewì rẹ̀. A rí i pé Ọláńrewájú Adépọ̀jù gan-an fúnra rẹ̀ jẹ́ alárògún àti alárọ̀jinlẹ̀. Ìdí ni pé, àpẹẹrẹ àtinúdá fara hàn nínú àgbékalẹ̀ oríkì Oldùmarè tó jẹ yọ nínú àwọn ewì rẹ̀ tí a ṣà yàn. Ẹ̀sìn Ìsìláàmù tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀sìn àjòjì tó wọ àwùjọ Yorùbá ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù yàn láàyò. Èyí fara hàn nínú àgbékalẹ̀ èrò rẹ̀ nípa Olódùmarè, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òjò àṣà ìbílẹ̀ rẹ̀ borí ọ̀dá ẹ̀sìn ìgbàlódé tí ó yàn láàyò nínú àpẹẹrẹ oríkì Olódùmarè tó hàn nínú ewì rẹ̀.A ṣe àmúlò àfojúsùn àwọn agbátẹrù tíọ́rì ìfojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀ láti ṣe àyẹ̀wò ipa tí ojúùwòye Ọláńrewájú Adépọ̀jù kó nínú àgbékalẹ̀ oríkì Olódùmarè tó hàn nínú ewì rẹ̀. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ohun tí ó ń dunni, ní ń pọ̀ lọ̀là ẹni. Ohun tó ń dun Ọláńrewájú Adépọ̀jù nípa ìhà tí àwọn ẹ̀dá ènìyàn kọ sí ohun àyíká wọn láìnáání agbára àìrí tí ó ṣe okùnfà àwọn nǹkan náà ni ó bí oríkì Olódùmarè tí ó kì nínú ewì rẹ̀. ìgbàgbọ́ akéwì yìí ni pé, bí àwọn ènìyàn bá ní ìbẹ̀rù Olódùmarè pẹ̀lú agbára Rẹ̀ tí ó tayọ agbára èyíkéyìí, wọn yóò máa gbé ní ìrẹ́pọ̀ àti àlàáfíà láwùjọ wọn. Bí a bá wo èrò akéwì yìí, a ó rí i pé kò yàtọ̀ sí ojú tí àwùjọ Yorùbá fi wo Olódùmarè gan-an. Ìdí nìyí tí a fi ṣàlàyé ṣókí nípa ojú-àmúwayé àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè, bí ó ti hàn nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú bí Ìdòwú (1960), Ọlájubù (1978), Adéoyè (1979), Dáramọ́lá àti Jéjé (1987), Ajíbádé (2009) àti Ìṣọ̀lá (2010) pẹ̀lú àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. A tún rí i pé oríkì kó ipa tí ó pọ̀ nínú ìlànà tí àwọn Yorùbá ń gbà ṣe àfihàn èrò wọn, pàápàá nípa àbùdá-àdáni àti àbùdá-àdámọ́ nǹkan. Èyí ló mú wa ṣe àfihàn èrò àwọn onímọ̀ ìṣáájú nípa ìwúlò oríkì. Lára àwọn onímọ̀ bẹ́ẹ̀ ni Láṣebikan (1958), Babalọá (1967), Ayọ̀rìndé (1973), Welch (1973), Babalọlá (1975), Barber (1984), Ọlátúnjí (1984), Ajíbádé (2009) àti àwọn mìíràn.

Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ márùn-ún pàtàkì tí a ṣe àfojúsùn wọn nínú ìtọpinpin àgbékalẹ̀ oríkì Olódùmarè tí ó ṣú yọ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni ó fi akéwì náà hàn gẹ́gẹ́ bí èyí tí ìlànà ìṣafọ̀ rẹ̀ bá kókó-èrò àwọn agbátẹrù tíọ́rì ìfojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀ mu. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ náà dá lórí bí ó ti ṣe àfihàn Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí Aṣẹ̀dá, Akọ́dá, Aláṣẹ lórí ohun gbogbo, Alágbára àti Ọba-Àìkú. Ìjẹyọ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ máràárùn yìí ni ó fi ìdí ìwádìí yìí múlẹ̀ pé àwọn Yorùbá tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù fi èrò ọkàn rẹ̀ ṣe àgbágbè fún, ni wọ́n rí Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí ẹ̀mí-àìrí kan tí ó dá gbogbo nǹkan.

## Tíọ́rì Àmúlò

Ẹrí-máa-jẹ́-mi-nìṣòó ni tíọ̀rì jẹ́ fún àwọn olùwádìí àti láméètọ́. Bí ìgbà tí ènìyàn sọ pé iná ń jó lórí omi, tí ó sì rí eérú rẹ̀ kó han àwọn tó ń jà á níyàn ni tíọ̀rì jẹ́ fún àwọn tó ń wá fìn-ín-ìn ìdí kókó nípa àwọn ohun àyíká wọn. Bí a bá tilẹ̀ wo ìwádìí tí ó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ nípa èrò-ìjìnlẹ̀ àti ojú-àmúwayé àwọn ẹ̀dá kan, ó ta yọ ohun tí a lè máa fi ẹnu lásán ròyìn rẹ̀. Ohun tí ó ṣe pàtàkì ni pé, olùwádìí bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ wádìí òkodoro nípa ohun tí ó ṣe okùnfà èrò-ìjìnlẹ̀ àwọn ènìyàn náà. Ibi ìwádìí òkodoro ni yóò ti ní àǹfààní láti tọ́ka sí àfijọ tí ó rí nínú àfiwé èrò-ìjìnlẹ̀ àwọn ènìyàn náà pẹ̀lú ìṣẹ̀lẹ̀ tó fojú hàn. Fún ìdí èyí, bí láméètọ́ bá fẹ́ wẹ̀ yán kànhìnkànhìn nípa ìwádìí rẹ̀, tíọ̀rì ni yóò ràn án lọ́wọ́.

**Tíọ̀rì Ìfojú-Èrò-Ọkàn-Aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀**

Abala kan nínú ọ̀wọ́ àwọn agbátẹrù tíọ̀rì ajẹmọ́-ìṣe-ọkàn ni àwọn tí wọ́n dá tíọ̀rì yìí sílẹ̀. Ohun tí ó ṣe okùnfà àgbékalẹ̀ tíọ̀rì yìí ni pé, púpọ̀ nínú àwọn láméètọ́ tíọ̀rì ajẹmọ́-ìṣe-ọkàn jẹ́ onímọ̀ lítíréṣọ̀. Èyí gan-an ló mú wọn gbà pé, bí láméètọ́ bá fẹ́ mọ̀ nípa àkóónú lítíréṣọ̀ kan, ó lẹ́tọ̀ọ́ kí ó kọ́kọ́ mọ orírun lítíréṣọ̀ náà. Ibi ìtọpinpin orírun lítíréṣọ̀ tí àwọn ènìyàn ṣẹ̀dá rẹ̀ ló mú àwọn láméètọ́ afojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀ dábàá ṣíṣe àyẹ̀wò ohun tí ó gún aṣafọ̀ ní kẹ́ṣẹ́ láti gbé lítíréṣọ̀ kan jáde. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé, bí láméètọ́ bá ti mọ èrò ọ̀kan olùṣẹ̀dá iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀, yóò rọrùn fún un láti ṣe àwárí ìtumọ̀ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó bá jẹ́ àkóónú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀. Lára àwọn agbátẹrù tíọ̀rì yìí ni Fredson Bowers, Thomas G. Tanselle, Mckenzie D.F., McGann Jerome, Ryle Skinner, Daniel C. Dennet àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Èrò àwọn Ẹgbẹ́ Onímọ̀ afojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀ yìí gbára lé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Nítorí náà ni wọ́n fi pè é ní authorial intention theory. Èyí ni a ṣe ìfaramọ́lé fún láti fi ṣe àyẹ̀wò afọ̀ ewì alohùn Yorùbá. Ìdí nìyí tí a fi pe tíọ̀rì yìí ní ìfojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀. Fredson (1999:114) sọ pé:

> Authorial intention is of great practical concern to some textual critics. These are known as intentionists and an identified with the Bowers–Tansells school of thought. Their conditions, as one of their most important goals is the recovery of author's intentions generally final intentions) when preparing a wok of arts for the press.

(Ìfojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀ gbára lé iṣẹ́ takun takun tí ó jẹ mọ́ àyẹ̀wò afọ̀. Àwọn yìí ni a mọ̀ sí afojú-èrò-ọkàn-aṣafọ̀- wo-lítíréṣọ̀ tí a tún máa ń sà ní àmì nípa iṣẹ́ tí Bowers-Tanselle tí ó jẹ́ olùdásílẹ̀ tíọ̀rì yìí ti ṣe kalẹ̀. Ohun tí ó jẹ wọ́n lógún jù lọ ni àwárí ìmọ̀ nípa èrò-ọkàn òǹkọ̀wé ni òpin èrò rẹ̀ lápapọ̀ nígbà tí ó bá ń ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́-ọnà fún àwọn òǹtẹ̀wé).Kedere ló hàn nínú àyọlò òkè yìí pé, àwọn agbátẹrù tíọ̀rì yìí tẹ̀ lé èrò àwọn olùdásílẹ̀ rẹ̀ tí í ṣe Bower àti Tanselle (1967). Ìwádìí fi hàn pé olúborí èrò-ọkàn òǹkọ̀wé nígbà tí ó bá ń ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀ máa ń hàn nínú iṣẹ́ tí ó ṣe. Èyí ni àwọn agbátẹrù tíọ̀rì yìí fi gbà pé kí láméètọ́ máa tọpinpin ìṣẹ̀lẹ̀ tó wáyé ní (milieu) àkókò tí òǹkọ̀wé/aṣafọ̀ ṣe iṣẹ́ lítíréṣọ̀ rẹ̀, ó sì yẹ kí láméètọ́ lè ṣe àwòmọ́ kókó-ọ̀rọ̀ inú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítíréṣọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú ìrírí òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ tó gbé e kale, (Bower àti Tanselle 1967, pg 217). Bákan náà ni ó yẹ kí láméètọ́ múra sí ìtúpalẹ̀ kókó-èrò aṣafọ̀ gan-an ju abala mìíràn nínú iṣẹ́ tó ń ṣe. Wọ́n tún gbà pé kò sí lítíréṣọ̀ tí a yẹ̀ wò, tí kò ní í sí àpẹẹrẹ ìgbé ayé òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ níbẹ̀ àti pé àwùjọ ló ń gbin ìrírí sí ọkàn òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀. Ní pàtàkì jù lọ wọ́n gbà pé ìrírí òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ nínú àwùjọ ni ó máa ń jẹ́ olúborí nínú àgbékalẹ̀ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀, (Fredson 1999, pg 114).

**Iṣẹ́ Onímọ̀ Ìṣáájú lórí Èrò-Ìjìnlẹ̀ àti Ìgbàgbọ́ Àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè**

Létò-létò bí yangan ti ń to ọmọ rẹ̀, náà ni àwọn Yorùbá ń ṣe àgbékalẹ̀ ìgbé ayé wọn. Ìpele ètò kọ̀ọ̀kan tí àwọn Yorùbá ń ṣe nínú àwùjọ wọn ni ó gbára lé ojúùwòye wọn nípa bí ó ti yẹ kí àwọn nǹkan náà rí. Èrò báyéṣerí wọn yìí, ni ó bí ìgbàgbọ́ wọn nípa ẹ̀mí-àìrí kan tí kò sí ẹ̀dá tó ga jù ń lọ. Ẹ̀mí-àìrí yìí náà ni wọ́n tún gbà pé Ó dá àwọn ẹ̀mí-àìrí mìíràn tí agbara wà lọ́wọ́ wọn. Lọ́nà àkọ́kọ́, àṣẹ tí nǹkan fi ń ṣelẹ̀, tí

ìṣẹ̀lẹ̀ náà ń jẹ́ àgbàyanu àti ìjọlójú ni àwọn Yorùbá fi ń gbé òṣùbà káre fún ẹ̀dákẹ́dàá. Nítorí náà, wọ́n rí i pé àṣẹ agbára àìrí tó ju ti gbogbo àwọn ẹ̀dá yòókù láyé àti lọ́run ni Olódùmarè ń lò láti darí ayé, ọ̀run àti ibikíbi tí ó wà tí ènìyàn kò mọ̀. Ṣáájú kí bẹbẹ tó máa bẹ ni Olódùmarè ti ń bẹ, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá Olódùmarè yìí náà ni Ó ti ṣe ètò bí gbogbo nǹkan ti rí ní ìpìlẹ̀ṣẹ̀, tí ẹnikẹ́ni kò fi ní àǹfààní láti gba ipò mọ́ Ọn lọ́wọ́ láyé, lọ́run àti ní ibi gbogboo.Ìdòwú (1962:17) fi èyí hàn nínú ìwádìí rẹ̀ nípa Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá tí ó tóbi jù lọ. Òun ni ó rán àwọn Imọlẹ̀ sí òde-ayé gẹ́gẹ́ bí alágbàwí fún Un lọ́dọ̀ àwọn ẹ̀dá ènìyàn. Ìdí ni pé, Ọba-Àìrí ni Olódùmarè. Ìdòwú (1962:17) fi yé wa pé:

The existence of Olódùmarè eternally has, for all practical purpose, been taken for granted as far back beyond question it is upon this basic faith that the whole superstructure of Yorùbá belief rests. Then there are the divinities especially the principal ones. All the indication which have come down to us are that they were all brought into existence by Olódùmarè that they might be his ministers in carrying out, each in his own office, the functions connected with the creation and theoretic government of the earth.

(Ipò tí Olódùmarè wà, fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ìgbìdánwò tó ti wáyé di ohun àfojúyẹpẹrẹ wò ní èyí tí ó kọjá òye ẹni. Èyí gan-an ni ó bí èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ní gbòòrò. Ìgbàgbọ́ wọn tún ni pé àwọn òrìṣà kan wà, pàápàá jù lọ àwọn àgbà òrìṣà. Àwọn àpẹẹrẹ àti àmì tí ó ti sọkalẹ̀ sí wa fi hàn pé Olódùmarè ni ó rán wọn wá sí òde-ayé gẹ́gẹ́ bí àwọn ìránṣẹ́ Rẹ̀ láti wá ṣe ojúṣe kọ̀ọ̀kan tí Ó rán wọn wá ṣe, bí èyí tí ó jẹ mọ́ ìṣẹ̀dá ayé àti àkóso ètò kọ̀ọ̀kan ní orílẹ̀-ayé.)

Ìhun ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá ni onímọ̀ yìí fi yé wa pé ọ̀dọ̀ Olódùmarè ni ó ti ṣẹ̀ wá. Bí wọ́n ti gbẹ́kẹ̀ lé Olódùmarè àti àwọn tí Ó rán sí wọn láti wá ṣe ojúṣe kọ̀ọ̀kan ní òde-ayé bí ìṣẹ̀dá ilé-ayé àti àkóso àwọn ètò kọ̀ọ̀kan tí ó rọ̀ mọ́ ètò ìgbé ayé àwọn ènìyàn ni ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn gbára lé. Alágbàwí ni àwọn ẹ̀dá náà jẹ́ fún wọn lọ́dọ̀ Olódùmarè tí wọ́n gbàgbọ́ pé ó dá àwọn. Imọlẹ̀ tàbí òrìṣà ni wọ́n ń pe àwọn ẹ̀dá tí à ń wí yìí. Ìgbàgbọ́ wọn pé Olódùmarè ni ó dá àwọn pẹ̀lú àwọn òrìṣà àti gbogbo nǹkan tí ó wà láyé àti ọ̀run fi ara hàn nínú onírúurú oríkì àti orúkọ tí wọ́n máa ń pe Olódùmarè. Lára irúfẹ́ oríkì bẹ́ẹ̀ ni Adẹ́dàá, Aṣẹ̀dá, Atóbijù, Alábẹ́nú-àá-sá-sí, Alayé lọ̀run àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀.

Olódùmarè ni gbogbo agbára ń bẹ ní ìkápá Rẹ̀. Agbára wí-bẹ́ẹ̀-jẹ́-bẹ́ẹ̀ àti àṣẹ lórí bí ohun gbogbo ti ń yí padà. Olódùmarè ni Alábàáláṣẹ, Olùdarí-ayé, Olùṣẹ̀dá-ayé àti Atáyérọ. Òun ni ó ṣẹ̀dá ohun gbogbo tí Òun gan-an kò sì ní ìpìlẹ̀. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá tún rọ̀ mọ́ ọn pé Olódùmarè ni Ọba tí yóò pẹ́ títí ayé kánrin kése. Kò sí ẹ̀dá tó mọ ìpìlẹ̀, àṣíri tàbí bí Olódùmarè ti tóbi tó. Ìdòwú (1962:33) tún fi yé wa pé:

That is, He is the Head and Overlord of all in heaven and on earth; indisputably absolutely unique and beyond comparison in majesty and fullness of attributes.

(Ìyẹn ni pé, Òun ni Olórí àti Olúwa gbogbo ohun tí ń bẹ lọ́run àti òde-ayé; Aláìlẹ́gbẹ́, Aláìláfijọ tí ó sì dá yàtọ̀ nínú ọlá àti gbogbo àbùdá Rẹ̀.)

Olódùmarè ni ó ṣẹ̀dá ohun gbogbo tí ó sì ń ṣe àkóso lé wọn lórí láyé àti òde-ọ̀run. Orúkọ Olódùmarè ta yọ ti gbogbo àwọn ẹ̀mí-àìrí àti àwọn ẹ̀dá yòókù káàkiri gbogbo ìbikíbi tí wọ́n wà. Àwọn ẹ̀dá ènìyàn kan ń mú lára àbùdá orúkọ Rẹ̀ láti fi sọ ara wọn lórúkọ, kí àṣẹ agbára Rẹ̀ lè máa ṣẹ nínú ètò ayé wọn. Olódùmarè kò ní àfijọ nínú ìrísí, ìṣesí, agbára àti ẹ̀mí. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi ń pe Ọlọ́run ní Ọlọ́fin-Ọ̀run, Akọ́dá, Aṣẹ̀dá, àti orísìí àwọn orúkọ ńlá ńlá mìíràn. Ẹsẹ-Ifá Ògúndáborógbè náà tilẹ̀ ṣe àfihàn lááríjà Olódùmarè, gẹ́gẹ́ bí awo Ifá Adéwùmí ti kì í fún wa pé:

Bí wọn bá dá Ògúndáborógbè sílẹ̀Ọmọ awo a fẹ́ jẹ̀Ọmọ awo a fẹ́muỌmọ awo a fidí ọ̀rìnrìn balẹ̀

A díá fún Olódùmarè

5 Ọba Asọhun-rẹbẹtẹ-kárí-ayéKò sí ohun tí Ọlọ́runò lèṣeBíỌlọ́runbáṣòjòAṣọ̀dáAmúkanòù 10 A ṣèkanA dàbí ọyẹ́Kò sí ohun tí ọlọ́run ò lè ṣe.Àyọlò òkè yìí gan-an ló fi èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá hàn nípa Olódùmarè. Kódà, Ifá tilẹ̀ menu ba ipò Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó tóbi jù lọ pé:Mo bérin jàMo dérinMo bẹ́fọ̀n jàMo dẹ́fọ̀n.Mo bỌ́lọ́run jàỌlọ́run ló dá mi.Nínú àyọlò òkè yìí, ọ̀rọ̀-ìṣe dá níbẹ̀ jẹ́ alómọ́ọ̀fù onítumọ̀ pọ́n-ọ́nna tí ó túmọ̀ sí "ìṣẹ̀dá" dípò "dídáni" lójú ìjà tí ó lè jẹ́ eréfẹ̀ẹ́ ìtumọ̀ rẹ̀ nínú ìhgun àyọlò náà. Ohun tí ọ̀rọ̀-ìṣe "dá" tí ó túmọ̀ sí ìṣẹ̀dá náà ṣe àfihàn rẹ̀ ni ojú-àmúwayé àwọn Yorùbá nípa Olódumarè gẹ́gẹ́ bí Adẹ́dàá ohun gbogbo tí ó sì jẹ́ orírun fún ohun gbogbo, yálà ohun tí ó jẹ́ abẹ̀mí tàbí àwọn ohun aláìlẹ́mìín. Ọlájubù (1978:1) náà sọ pé "Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé Ọlọ́run ló dá ayé tó sì dá àwọn ẹ̀dá inú rẹ̀ àti pé gbogbo àwa ẹ̀dá wá sínúu rẹ̀ bí ẹni tó lọ ná ọjà ni tí yóò sì pàda relé láti lọ jábọ̀." Ohun tí Ọlájubù (1978:1) gbà lérò nínú àyọlò òkè yìí ni pé, kò sí ẹ̀dá ayé àti ọ̀run kan tí kò sí ní abẹ́ àkóso Olódùmarè, gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó máa ń hàn nínú ewì alohùn àwọn Yorùbá. Èrò yìí ni ó jẹ́ kí àwọn ènìyàn máa kó ara wọn ní ìjánu ní òde-ayé. Ìgbàgbọ́ pé agbára Ọlọ́run tí ó tóbi jù ká wa tí Ó sì ń ṣe àkọsílẹ̀ gbogbo ìṣesí àti ìhùwàsí wa ni ó ká wa lọ́wọ́ kò. Èyí ni yóò sì jẹ́ ẹ̀san àti èrè iṣẹ́ wa lóde-ayé àti ọ̀run. Ọ̀kan ṣoṣo ni Ọlọ́run, Òun ni ó sì ga ju gbogbo ẹ̀dá lọ.

Àwọn onímọ̀ tí a ṣe àmúlò èrò wọn lókè yìí fi yé wa pé onírúurú orúkọ tí àwọn Yorùbá ń pe Olódùmarè ní ìtumọ̀ sí wọn. Olúborí èròǹgbà àwọn Yorùbá gan-an lórí àwọn orúkọ bẹ́ẹ̀ ni ọ̀wọ̀ àti ọlá tí wọ́n ń fún Olódùmarè nínú èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ wọn nípa Rẹ̀. Wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ èrò yìí láti máa fi ṣe ètò ayé wọn, kí ayé wọn lè gún régé. Àyẹ̀wò èrò àwọn onímọ̀ ìṣáájú àti àwọn ìpohùn Yorùbá tí a ṣe àfihàn rẹ̀ wọ̀nyí tọ́ka sí i pé ẹ̀dá kan ṣoṣo tí gbogbo ayé àti ọ̀run gbà gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́run jẹ́ Ọba-Àìrí, Adẹ́dàá, Arínúróde àti Olùmọ̀ràn-ọkàn. Alágbára ni Ọlọ́run, tí kò sí ẹ̀dá tí ó tóbi tó O nínú ọlá àti ipò gẹ́gẹ́ bí èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá.

**Ìjẹyọ Èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ Àwọn Yorùbá nípa Olódùmarè nínú Ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù**

Àwọn ohun tí ó bí èrò-ìjìnlẹ̀ akéwì yìí nípa Ọlọ́run pọ̀, ṣùgbọ́n olúborí wọn ni ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ rẹ̀. nínú àwọn àṣàyàn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù tí a fi ṣe òdìwọ̀n fún ìwádìí wa, a rí i pé ó máa ń fi èrò-ìjìnlẹ̀ rẹ̀ nípa Ọlọ́run ṣe ìtọ́sẹ̀ fún àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí ó ní lọ́kàn nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ rẹ̀. ní pàtàkì jù lọ, yóò kí Ọlọ́run tàbí kí ó kì Í láti ṣe àpọ́nlé Rẹ̀ pé Òun ni ó lè yanjú ìṣòro ẹ̀dá, bí ó bá jẹ́ pé kókó-ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìṣòro ni ó jẹ ẹ́ lógún. Ó ṣòro láti rí kókó-ọ̀rọ̀ ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù kan, tí kò ní mú ẹnu bá ipa tí Olódùmarè kó lórí ọ̀rọ̀ náà nínú ìgbé ayé ẹ̀dá. Èyí ló mú akéwì yìí gbà pé Olódùmarè ni Ọba Akọ́dá ayé, Òun náà sì ni Aṣẹ̀dá ayé àti ọ̀run. Ó tún gbà pé Olódùmarè ni Aláṣẹ lórí ohun gbogbo. Bákan náà ẹ̀wẹ̀, ó hàn nínú ewì rẹ̀ pé Alágbára ni Ọlọ́run lórí ohun gbogbo. Ọlọ́run ni Ọba tí kì í kú, tí kì í ṣá, tí kì í sì díbàjẹ́. Ẹ jẹ́ kí á ṣe àyẹ̀wò àwọn kókó-ọ̀rọ̀ wọ̀nyí, bí ó ti ṣú yọ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan.

**Olódùmarè: Ọba-Akọ́dá-Ayé**

Èrò akéwì nípa orúkọ yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú ojúàmúwayé àwọn Yorùbá nípa orúkọ náà. Ìtumọ̀ rẹ̀ gan-an ni pé, kò sí ẹni tí ó dá Olódùmarè. Òun ni ó kọ́kọ́ wà ṣáájú ohun gbogbo. Èyí máa ń hàn nínú ìwúre tàbí ìjúbà àwọn àgbà ọ̀jẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá pé "ìbà

akọ́dá ayé tí Ó dá tiẹ̀ sórí ewé”. Olódùmarè ni wọ́n ń tọ́ka sí ní abala ibi tí wọ́n bá ti lo èdè yì í. Ẹ wo àpẹẹrẹ ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù tó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:Ọbaàmi ọ̀gbàgbàTí í gba ni lágbàtánAlábẹ́nú à á ṣáá síỌba Abìyẹ́ gbòòrò gbooroAkọ́dá ayé ni Ọ́Ìwọ lo ti ń bẹKí bẹbẹ ó tó máa bẹỌbaà mi Òkè ló ti ń wàKéèyàn ó tóó wà.(Ayé pé Méjì; Hot: 21-32)

Bí a bá wo àyọlò òkè yìí, Ọláńrewájú Adépọ̀jù júwe Olódùmarè bí Ohun kan tí a kò mọ olùṣẹ̀dá rẹ̀. ní ìlà karùn-ún sí ìlà kẹsàn-án àyọlo náà, akéwì ṣe àfihàn ipò tí Olódùmarè wà sí àwọn nǹkan tó wà nínú ayé, pàápàá jù lọ, ẹ̀dá èniyàn tí ó tọ́ka sí ní ìlà kẹsàn-án. Ohun tí akéwì yìí ní lọ́kàn nípa “bẹbẹ tó ń bẹ” ni pé, àwọn nǹkan tó wà ní ilé ayé àti ọ̀run jẹ́ nǹkan tó ń bẹ. Ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé gbogbo wọn ni Olódùmarè ti wà ṣáájú wọn.

Ohun tó rújú gbáà ni fún àwọn èniyàn, bí a bá ń sọ nípa Ọlọ́run gẹ́gẹ́ bí Ọba tí Ó jẹ́ akọ́dá. Ìdí ni pé, wọn yóò máa rò pé, taa ló dá Ọlọ́run gan-an?

Ọláńrewájú Adépọ̀jù kọ́kọ́ mú ẹ̀rí àwọn onímọ̀ nípa ìṣẹ̀dá ẹ̀dá lò láti bu ẹnu àtẹ́ lu èrò àwọn tí ń sọ pé kò sí Ọlọ́run. Ìmọ̀ àwọn onímọ̀ nípa ìṣẹ̀dá ẹ̀dá gbà pé ibi omi lọ́gbọ́lọ́gbọ́ tí ó jáde lára akọ sí ara abo ni ìṣẹ̀dá ẹ̀dá ti bẹ̀rẹ̀. Èyí ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù náà ń wí ní ìlà kọkànlá sí ìlà kẹẹ̀ẹ́dógún. Ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Ọlọ́run ló ń dá àrà sí omi náà tí ó fi ń di ọmọ nínú obìnrin. Akéwì yìí fẹ́ kí á gbà pé, bí kò sí àṣẹ Ọlọ́run, irúfẹ́ nǹkan tí ó tọ́ka yẹ̀ií kò lè ṣẹlẹ̀. Ẹ̀rí mìíràn tí akéwì yìí tún fit a ko èrò àwọn tí ń sọ pé kò sí Ọlọ́run yìí ni pé, ìyàtọ̀ wà nínú gbogbo ẹ̀dá tó wà láyé. Ó ní:Wèrè ọ̀làjú

Aṣé bóo ti mọnú-ún rò mọ nì-ín?O lápáỌ lẹ́sẹ̀Oò ṣe bọrọgidi gẹ́gẹ́ bí igi 5

Ọba-Òkè ò dá ọ gẹ́gẹ́ bí àwọn kòkòrò lásánỌ yapa séwúrẹ́ pẹ̀lú àgùntànBÓlúwaà mi bá fi ọ́ búùyànTóo bá rí bí àwọn ìnàkí lásánAlákọrí

10Kí loò bá wá dáwùjọ adáríhurunBóo bá rí bí ẹranko tí ń gbó bí ajáTaa lo fẹ́ bá rojọ́ gangan?BỌ́baaṣẹ̀dá bá fi ọ́ yàyààkuyà ńkọ́?Bóo bá wà níjù

15Taa lo le fẹ̀hónú hàn?(Alágbara; Hot: 33-57)

Àyọlò òkè yìí kún fún ẹ̀rí tí akéwì fi ṣe àgbégbè fún èrò-ìjìnlẹ̀ rẹ̀ nípa Ọlọ́run. Ó fi ṣe àtakò sí ojú àmúwayé àwọn tí wọ́n gbà pé kò sí Ọlọ́run. Lójú tirẹ̀, ó gbà pé Ọlọ́run ló dá gbogbo nǹkan bí ó ti wù ú, tí kò sì sí ẹni tó yẹ Ẹ́ lọ́wọ́ wò. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé, bí èniyàn kò tilẹ̀ rí Ọlọ́run sójú, ó yẹ kí ó lè kíyèsí àwọn ohun àdìítú àti kàyéèfì ńlá tó wà ní àrọ́wọ́tó rẹ̀, kí ó sì ronú pé àwọn nǹkan náà kò dédé lalẹ̀ hù. Ìgbàgbọ́ àti èrò-ìjìnlẹ̀ ló papọ̀ sínú àgbékalẹ̀ afọ̀ tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù fi ṣe àpèjúwe Ọlọ́run. Ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, bí a kò mọ erin, bí a bá ti ń gbóhùn erin, ó yẹ kí á mọ bí erin ti tóbi tó. Èniyàn tí kò rí Ọlọ́run rí, ó yẹ kí ó rí àpẹẹrẹ Ọlọ́run lára gbogbo nǹkan tó wà láyé. Èyí sì fi hàn pé, Ọlọ́run Ọba ni Àkọ́kọ́, Ọ̀gá, Olórí àti Aṣáájú ohun gbogbo láyé àti ọ̀run.

**Ọlọ́run: Ọba-Aṣẹ̀dá-Ohun-gbogbo**

Nínú àgbékalẹ̀ àwọn àṣàyàn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù, a rí àpẹẹrẹ pé bí kò ti sí ẹ̀dá tí ó dá Ọlọ́run, náà ni ó jẹ́ pé Ọlọ́run yìí ni ó dá ohun gbogbo. Ìṣẹ̀dá èniyàn, ẹranko, ẹyẹ,, igi, ewéko, kòkòrò, ilẹ̀, omi, ojú ọ̀run, àpáta, afẹ́fẹ́, òòrùn, ìrànwọ̀, ọ̀ṣùpá, òórùn àti gbogbo àwọn ẹ̀mí-àìrí wà lọ́dọ̀ Ọlọ́run. Wẹ́kú ni èyí ṣe pẹ̀lú ìgbàgbọ́ àti èrò-ìjìnlẹ̀ àwọn Yorùbá nípa Ọlọ́run. Ọláńrewájú Adépọ̀jùsọ pé:Ìwọ aṣiwèrè tóo lỌ́lọ́run ò síO ti ṣe dénú ìyáà rẹ?Rántí péOmi ni ọ́Ká tó sọ ọ́ dọmọ

5Akọ́dá dá ọAṣẹ̀dá dá ọ tánÌwọ́ gbàgbéWọ́n lÓlúwa ńÒ lóò gbà(Alágbára; Hot: 8-19)

Nínú àyọlò òkè yìí, Ọláńrewájú Adépọ̀jù ṣe àpèjúwe bí Ọlọ́run ti jẹ́ Adẹ́dàá ohun gbogbo. Ó fi ìṣẹ̀dá èniyàn ṣe àkàwé bí Ọlọ́run ti ń ṣẹ̀dá nǹkan. Ó fi yé wan í ìlà àkọ́kọ́ àyọlò náà pé, èniyàn kì í fò dé inú obìnrin bí kò bá lọ́wọ́ Ọlọ́run nínú. Ó ni Akọ́dá ní Ọlọ́run, òun náà sì ni Aṣẹ̀dá tó ń ṣ ẹ̀dá nǹkan. Ẹ tún wo àpẹẹrẹ yìí náà:Ọbaà mi Ọ̀gbàgbàTíí gbanni lágbàtánỌba Alábẹ́ à á sáá síỌba Abìyẹ́ gbòòrò gbooroỌba tíí gbénni ga lójú arínni

5Gbòǹgbò-àṣírí-inú-àwọn-àṣíríA-tóó-fara-tì-má-bẹ̀rù-ọ̀tẹ̀Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ọ yín ẹ̀yin èèyànMo sì dúpẹ́

lọ́wọ́ Ọlọ́run ÀánúỌba A-tóó-bọ-bí-orí Ọba Aláàfin-ÀjọbọẸni-mímọ́-ọláAfunfun-tún-funfunBàbáà-mi-ìkọ̀kọ̀Bàbáà-mi-ìbábá Arúgọ́gọ́-ináAbòruru-ọ̀rọ̀Adáná-finá-yáAdáná-finá-jeAlágbárí-iná Ẹ̀rù-baba-ọ̀jẹ̀jẹ̀Àríìrọ́-àláÒgìrì-bá-jìganÒgìrì-bá-jìgòPitú-pitú-ọlá Àríkí-ǹ-tàkíÒkìtì gbọnìn-gbọnìnBíríkítí-ọláBìrìkìtì-ọlàOjúlówó-ọgbọ́n Òdodo-ìmọ̀rànỌ̀dáyé-ǹ-dáyéỌ̀dàyè-ǹ-dayèAláyégún-ayéAlálẹ̀dẹ-ọ̀run Àdìgún-un-sánmọ̀Ẹlẹ́dàá-ǹ-ṣẹ̀dáỌ̀dájú-ǹ-dámúỌ̀dàgẹ̀-ǹ-dagẹ̀Adápá-fi-lápá Adétí-lu-bí-ajereỌ̀ṣẹ̀dá-ǹ-ṣẹ̀dáỌ̀-dámú-ǹ-dámúỌ̀-dẹ̀sẹ̀-ǹ-dẹsẹ̀Ò-dórí-ǹ-dórí A-dórí-tán-fẹnu-siÒ-dáyé-ǹ-dáyéỌ̀-dàyè-ǹ-dayè(Oríkì Olódùmarè; Hot: 1-59)

Bí a bá wo àgbékalẹ̀ ìhun oríkì Olódùmarè tó wà lókè yìí, a ó rí i pé akéwì pilẹ̀ ṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ ti ń ròyè Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí ẹni tó dá ohun gbogbo àtinúdá akéwì náà ta yọ. "ó ṣe àtòjọ àwọn orúkọ tí ó fi ròyìn iṣẹ́ ìṣẹ̀dá ṣíṣe fún Olódùmarè láti ìlà ọgbọ̀n títí dé ìlà kejìdínláàádọ́ta. Orúkọ tí akéwì yìí pe Olódùmarè ní ìlà ọgbọ̀n sí ìlà kejìlélọ́gbọ̀n túmọ̀ sí Olùṣẹ̀dá ayé. Èyí ni ó ṣe lo ìlànà ìfọ̀rọ̀dárà fún ọ̀rọ̀ náà ní ìlà kejìlélọ́gbọ̀n sí ìlà kẹtàlélọ́gbọ̀n, tí ó fi pe Ọlọ́run ní "Ọ̀-dáyé-ǹ-dáyé àti Ọ̀-dàyè-ǹ-dayè". Lẹ́yìn èyí ni Ọláńrewájú Adépọ̀jù tún pe Ọlọ́run ní "Aláyégún-ayé" ní ìlà kẹ̀rìnlélọ́gbọ̀n àyọlò òkè yìí láti fi hàn pé òun náà ló dá ayé, tí ó sì ń ṣe ètò ayé tí ayé fi ń gún. Ní ti "Alálẹ̀de-ọ̀run" tí akéwì pe Olódùmarè ní ìlà karùnlélọ́gbọ̀n, ó túmọ̀ sí pé Ọlọ́run ni ó ni ibi tí à ń pè ní ọ̀run. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ojú ẹnikẹ́ni kò tó ọ̀run, síbẹ̀, èrò-ìjìnlẹ̀ àwọn Yorùbá hàn nínú àgbékalẹ̀ èrò akéwì yìí pé àyè kan ni òde-ọ̀run náà jẹ́ bí ayé ti rí yìí. nítorí náà, Ọlọ́run tí ó dá ayé yìí náà ni ó dá yìí. Nítorí náà, Ọlọ́run tí ó dá ayé yìí náà ni ó dá òde-ọ̀run náà.

**Ọlọ́run: Aláṣẹ-lórí-Ohun-gbogbo**

Nínú àwọn oríkì tí Ọláńrewájú Adépọ̀jù fi ki Ọlọ́run ni a tún ti rí àpẹẹrẹ àpèjúwe tí ó fi ròyìn Ọlọ́run gẹ́gẹ́ bí Aláṣẹ lórí ohun gbogbo. Ọ̀rọ̀ nípa àṣẹ jẹ́ ohun tó gba èrò-ìjìnlẹ̀ bí a bá fi ojú-inú wò ó. Ìdí ni pé, bí a bá pe ènìyàn ní aláṣẹ, ó gbọ́dọ̀ jẹ́ olúborí fún gbogbo ohun tí àṣẹ rẹ̀ wà lórí wọn. Fún ìdí èyí, àṣẹ tí Ọlọ́run ní lórí gbogbo ayé àti ọ̀run tayọ àṣẹ tí a lè fi ròyìn ènìyàn. Irúfẹ́ àṣẹ bẹ́ẹ̀ rọ̀ mọ́ àṣẹ ikú àti ààyè, àṣẹ àṣírí, àṣẹ ìkọ̀kọ̀, àṣẹ gbangba, àṣẹ wí-bẹ́ẹ̀-jẹ́-bẹ́ẹ̀ àti gbogbo ohun tí ń ṣẹlẹ̀ láyé àti ọ̀run. Àṣẹ yìí ni a lè fi ròyìn Ọlọ́run. Ẹ wo àpẹẹrẹ nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù yìí:

> Ilé ayé pé méjì lóòótọ́Bí Ọba Èdùmàrè ti fẹ́ràn ọmọ ẹ̀dá tóBó bá yáA tún dánni wò díẹ̀Ara a tún máa taniBọ́ba Èdùmàrè bá fẹ́A tún gbégbà dídùn déBáyé ṣe pé méjì ló ṣọ̀tọ̀ọ̀tọ̀(Ayé pé Méjì; Hot: 9-16) Àrà tó bá wu ẹ̀fúùfù lẹ̀lẹ̀ ní ń fi ewéko dá. Bí ó bá ti wu Fúlàní ní ń darí àwọn màálúù. Àṣẹ tí Olódùmarè ní lórí àwa ẹ̀dá ènìyàn ló fi ń tì wọ́n síbi tó bá wù Ú. Èyí ló hàn nínú èrò akéwì yìí. Bí ikú bá pa ènìyàn, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé Èdùmàrè ló fún ikú níàṣẹ láti gba ẹ̀mí ẹni náà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé, ewé kan kì í bọ́ lára igi kí Èdùmàrè má mọ̀ sí i. Àṣẹ tí Èdùmàrè ní lórí ohun gbogbo ló fà á, tí ohunkóhun kì í fi í ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn Rẹ̀ láì jẹ́ pé Ó mọ̀ sí i.

**Olódùmarè: Ọba-àìkú-àìṣá-àìdìbàjẹ́**

Èrò ìjìnlẹ̀ mìíràn tí a tún rí nínú ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù nípa Ọlọ́run ni agbára àìkú, àìṣá àti àìdìbàjẹ́. Èrò yìí ta yọ ohun àpérò tí àríyànjiyàn lè máa wáyé lórí rẹ̀. Ìdí ni pé, gbogbo àwùjọ àti ẹ̀sìn tó gbà pé Ọlọ́run wà ni wọ́n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Ayérayé ni Ọlọ́run. Èyí túmọ̀ sí pé, Òun nìkan ni Ó wà ṣáájú ìṣẹ̀dá ohun gbogbo, Ó wà títí di òní, yóò sì tún máa bẹ kánrinkése. Èyí yàtọ̀ sí ètò ìgbé ayé àwọn ẹ̀dá bí igi, ilẹ̀, òkè, ènìyàn, ẹranko, omi, ẹyẹ, kòkòrò àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Ikú ń pa wọ́n, wọ́n ń dogbó, wọ́n sì ń yí padà. Ẹ wo àyọlò ewì tó wà nísàlẹ̀ yìí:

Ọjọ́ tọ́mọ èèyàn ò níí dájọ́ mọ́

Tó jỌ́ba-lókè ní ó kù lÁdájọ́

Lọ̀jọ́ tỌ́ba-lókè ó fògo fóhun gbogbo

Lọ̀jọ́ tí wọn ó sọ gbogbo òkè ńlá di pẹ̀tẹ́lẹ̀

Àtigi àtọ̀pẹ̀ ò níí wó mọ́

Gbogbo ilé ni ó wòó

Gbogbo ilẹ̀ ó sì di gbẹrẹfu

Bówó bá jónáAṣọ a jóná

Gbogbo ayọ́kẹ́lẹ́, a wá parun

(Ọjọ́ Ìdájọ́; Hot: 21-38)

Àyọlò òkè yìí fi hàn gbangba pé kò sí ohun tí kò ní òpin nínú gbogbo ohun tó wà láyé. Gbogbo ohun tí ó bá ti ní ìbẹ̀rẹ̀, gbogbo wọn ló máa ń ní òpin. Bí a bá kíyèsí gbólóhùn tó wà ní ìlà àkọ́kọ́ sí ìlà keji àyọlò òkè yìí, a ó rí i pé bí òpin bá dé sí ohun gbogbo, kò ní dé sí Ọlọ́run tí ó dá wọn. Èyí gan-an ni akéwì fi ròyìn agbára Ọlọ́run nínú ewì rẹ̀ lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan.

**Àgbálọgbábọ̀**

Iṣẹ́ yìí ṣe àfihàn ipa àti ipò oríkì láwùjọ Yorùbá. A rí i pé inú oríkì ni a ti lè rí ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ohun tó ṣodo sínú àṣà, ẹ̀sìn àti ojú-àmúwayé àwọn ènìyàn àwùjọ kọ̀ọ̀kan tí wọ́n ni oríkì. Onírúurú nǹkan ni àwọn Yorùbá ń ki oríkì rẹ̀. Wọn a máa ki oríkì ènìyàn, ẹyẹ, ewébẹ̀, oúnjẹ, kòkòrò, àwọn ẹ̀mí-àìrí, abàmì ẹ̀dá, òkú ọ̀run, Ọlọ́run, òkè, ilẹ̀, igi àti onírúurú ohun àfojúrí àti àfòyemọ̀ mìíràn. Iṣẹ́ yìí wo ìlànà tí àwọn Yorùbá ń gbà lo oríkì láti ṣe àfihàn èrò-ìjìnlẹ̀ wọn nípa Ọlọ́run. Àṣàyàn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni a fi ṣe òdiwọ̀n fún ìwádìí yìí.

Nínú àgbékalẹ̀ àwọn ewì Ọláńrewájú Adépọ̀jù, a rí àpẹẹrẹ oríkì Olódùmarè tí ó fi ṣe àpèjúwe àbùdá àti ìrísí Olódùmarè. Nínú èrò akéwì yìí, ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, kò pọn dandan kí á tọpinpin ibi tí Ọlọ́run ń gbé láti rí I sójú kí á tó gbà pé Ọlọ́run wà. Ohun tí akéwì yìí fẹ́ kí á mú lò ni ìrònújinlẹ̀ nípa àwọn ohun àyíká wa àti ìlànà ìṣẹ̀dá àwa ẹ̀dá ènìyàn láti bi ara wa pé, taa ló dá wọn? Bí a bá ronú jinlẹ̀ nípa àwọn nǹkan náà, akéwì yìí gbà pé èsì ìbéèrè náà ni pé ẹ̀mí-àìrí kan wà tí ó ṣẹ̀dá wọn.

Ìrírí nínú àwùjọ àti ìmọ̀ nípa ẹ̀sìn ìbílẹ̀, àṣà ìbílẹ̀, àwọn ẹ̀sìn àjòjì tó wọ àwùjọ Ọláńrewájú Adépọ̀jù ni a rí gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó bí èrò-ìjìnlẹ̀ rẹ̀ nípa Ọlọ́run sí i lọ́kàn. Èyí sì wà ní ìbámu pẹ̀lú ẹ̀rí tí àwọn agbátẹrù tíọ́rì ìfojú-èrò-aṣafọ̀-wo-lítíréṣọ̀ gbà pé a lè lò láti máa fi tọpinpin àkóónú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀.

**Ìwé-Ìtọ́kasí**


Adéoyè, C.L (1979): Àṣà àti Ìṣe Yorùbá. Ìbàdàn. Oxford University Press Ltd.

Adéoyè, C.L (1989): Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá. Ìbàdàn. Evans Brothers (Nig. Pub.) Ltd.

Ajíbádé, G.O. (2005): "Is there no Man with Penis in this Land? Erocticism and Performance in Yorùbá Nuptial Song". African Study Monographs 26 (2), 99-113.

Ajíbádé, G. O (2009): Finding the Female Voice: A Socio-Cultural Appraisal of Yorùbá Nuptìal Poetry. Germany. Rudiger Koppe Verlag.

Ajíbádé, G.O. (1999): "Yorùbá Women Govern Their Men: A Socio-religious Approach to Feminism". Ifẹ̀ Social Sciences Review, vol. 17. No. 2, o.i. 194-293.

Ajíbádé, G.O. (2002): "Àgbéyẹ̀wò Awo Ọ̀ṣun àti Àwùjọ Òṣogbo nínú Iṣẹ́-Ọnà-Ajẹmẹ́wì àti Ajẹmáwòrán", Ph.D. Thesis, Ifẹ̀. Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University.

Ajíbádé, G.O. (2003): "A Sociological Analysis of Yorùbá Male Personal Oríkì (Oríkì Àbísọ)". Ifẹ̀ Journal of Theory and Research in Education, (IJOTRE). o.i. 90-96

Ajíbádé, G.O. (2005): "A Socio-cultural StudyofAbiku songs in Yorùbá land" Ntama Journal of Music and Popular Culture, University of Mainz, 1-16.

Ajíbádé, G.O. (2005): "Negotiating Performance: Osun in the Verbal and Visual Metaphors". Bayreuth African Studies Working Papers. No. 4.

Ajíbádé, G.O. (2006): "Yorùbá Men, Yorùbá Women", In: Jones Adam (ed.). Men of the Global South: A Reader. New Haven: Zed Books. o.i. 375-376.

Ayọ̀rìndé, J.A (1973): "Oríkì" nínú Source of Yorùbá History Bíòbákú, S. (ed). Oxford. Clarendon Press. Pp 108.

Ayọ̀rìndé, J.A (1974): Ìgbésí-Ayé Ọba Akínyẹlé Olúbàdàn tì Ìbàdàn. Ìbàdàn. U.P.L.

Babalọlá, A. (1966[a]): The Contents and Form of Yorùbá Ìjálá. Oxford. Clarendon Press.

Babalọlá, A. (1966[b]): "Rárà Chants in Yorùbá Spoken Arts" Staff Seminar Paper, University of Lagos.

Babalọlá,A.(1967):ÀwọnOríkìorílẹ̀,Glasgow.Collin.

Babalọlá,A.(1973):OrinỌdẹFúnÀṣeyẹ,Lagos.Macm an Nig. Publishers.

Babalọlá, A. (1975): Àwọn Oríkì Bọ̀rọ̀kìnní, Ìbàdàn. Hodder and Stoughton Education.

Babalọlá, A. (2000): Àwọn Oríkì-orílẹ̀ Mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n. Longman Nigeria Plc.

Barber, K. (1979): "Oríkì in Òkukù town", Ph.D. Thesis, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifê

Barber, K. (1984b): "Difference, Dissent, and Contradiction in Yorùbá Oral Literature", paper presented at DALL seminar series, University. Ifẹ̀.

Barber, K. (1991): I Could Speak Until Tomorrow, Oríkì, Woman and the Past in a Yorùbá Town. Edinburg. University Press.

Dáramọ́lá, O. àti Jéjé A. (1987): Àṣà àti Òríṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ìbàdàn Oníbọn-Òjé Press, Nig. Ltd.

Ìdòwú, E.B. (1962): Olódùmarè God in Yorùbá Belief. Lagos. Longman Nig. Ltd.

Ìṣọ̀lá, A. (2010). Making Culture Memorable. Ìbàdàn. Hope Publications Ltd.

Ìṣọ̀lá, S.A. (2006):"Ìjẹyọ Èrò-ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ Àwọn Yorùbá Nípa Ìlò Oògùn Nínú Ìwòsàn Ìbílẹ̀ Ṣíṣe" (N.C.E Project, TASUED Ìjẹ̀bú-Òde).

Ìṣọ̀lá, S.A. (2014), "Àgbéyẹ̀wò Kókó-Ọ̀rọ̀ àti Ìṣọwọ́ló-Èdè Nínú Àṣàyán Ewì Alohùn Yewa-Àwórì" B.A. Longessay Department of Linguistics and African Languages. O.A.U Ilé-Ifẹ̀.

Ìṣọ̀lá, S.A. (2015): "Yorùbá Verbal and Non-Vebal Communication as a Tool for Democratic Cultural in Nigerian Education System" in ZUBA: JOURNAL OF LANGUAGES. Àbújá, School of Languages, FCT College of Education, Zuba-Àbújá. pp 208-220

Ìṣọ̀lá, S.A. (2016): "KÉKERÉ LÀ Á PÈÈKÀN ÌRÓKÒ: Ojú-Àmúwayé Yewa-Àwórì nínú Ewì Alohùn Ọmọdé". (Conference paper at YSAN 2016, University of Lagos, Lagos state.)

Ìṣọ̀lá, S.A. (2018), "Ìtúpalẹ̀ Ìṣọwọ́lò àti Àkóónú Ewì Alohùn Ọmọdé nílẹ̀ Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ní Ìpínlẹ̀ Ògùn" M.A. Thesis, Department of Linguistics and African Languages. O.A.U Ilé-Ifẹ̀.

Ọlájubù, O. (1978): Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìbàdàn. Longman Nig. Ltd.Adéoyè, C.L (1972): Orúkọ Yorùbá. Ìbàdàn. Oxford University Press.

Ọlátúnjí, O. (1982) "Classification of Yorùbá Oral Poetry" nínú Afọláyan, A (ed). Yorùbá Language and Literature. Pp 57-81.

Ọlátúnjí, O. (1984): Features of Yorùbá Oral Poetry. Ìbàdàan University Press PLC.

Ọlátúnjí, O. (1979): "The Yorùbá Oral Poet and His Society", Research in African Literatures, Vol. 10, No. 2, pp. 179-207.

Welch, S. (1973), "Oríkì in Traditional African Music"; UCLA, James. (1969). African Studies Center: African Arts. Vol. 3; No 1. Pp 56-59.